**OWE**

Oju ni a nmo aisepo, enu ni a nmo aisiyo, obe ti ko ni eran iduro ni emo.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

**Asoje**

Igbalaiye, aiye ko l'oyole. B'ole loni o le ro lola.

VOL. XIII No. 809 LAGOS SATURDAY DECEMBER 23, - DECEMBER 29, 1961. KOBO ... (2D)

# AWAMOTO MUNISIPA DA'SE SILE, NWON KO ITIYA BA'LU EKO.

Ni ojo Alamisi (Thursday) ose yi ni gorgo so, awon awamoto ak'ero ti Ijoba ibile ilu Eko, da ise sile kri (kin'wo ti nwon mbere a'i anfani miran ti nwon nfe ninu ise won, ti nwon so wipe awon Alase Munisipa ko da won lohun.

Opolopo awon enia, paapa awon osise ti nwon wa ni Mushin, Yaba, Ebute Metta ni ko ri oko wo nibi ise won, awon obinrin ti o nfe lo ra oja fun odun Keresimesi, gbogbo ibudo oko ero kun akunya ti ko si oko ero Munisipa ti yio ko won. Iya nla ni eyi koba opo enia.

A gbo w'pe awon Alase Munisipa ti da awon awamoto ti o da'se sile na duro, awon enia ti nwon da duro na fere to ogofa enia, nwon si ti bere si gba awon awamoto m'ran.

Ogbeni F. S. McEwen ni a gbo wipe o so fun awon Oniwe irohin pe on ti se ikilo fun awon awamoto na ki nwon maşe da'se sile sugbon nwon ko eti ikun si ikilo on na.

O tun tesiwaju pe ise ilu ni awon nse, awon ko si ni gbaye ki enikeni ise idiwo fun ise awon.

Enyin Awamoto, e f'eso se o.

## Apo Ikowo Ile Nigeria Fun Omo Ilewe



ENGLAND - Odomoda obinrin kan ti o s'or're nibi Afihan ti egbe Ajumosepo awon ilu ti o mba Gesi sepo (Commonwealth Exhibition) ti nwon se ni Bournemouth, Omi'dan Anne Cosser, omo odun merinla ni Olola Alhaji Abdulmaliki, Asoju ile Nigeria nilu Oyinbo fi apo ikowo ti ile Nigeria ta lore.

Awon ti o duro lowo won ni Bale ilu Bournemouth ati iyawo re Iyafin Scott

# ENIA META KU SINU IJA ILU OKIRIKA

Ija nla kan be sile nilu Okirika nibi ayeye isinku ti awon Ijo Tuboniju ati Koniju, awon egbe meji to wa nilu Okirika,

Igo, igi ati ckuta ni nwon nju s'arawon ti enia meta fi ku.

Opolopo awon olopa ni nwon ti ko lo silu na lati le d'oro si ija na nwon si ti ba ile pupo je. ohun ti a gbo wipe o fa ija yi wa ri awon Ijo kan ti nwon lo fa isa ti awon ap... fi nse ayeye isinku na ha.

# Ina Jo Ile Apepe Kan ni Ajokanle

ENUGU– Ile Alapepe kan ti owo re to egbeta poun ti o ni iyara mefa, (Six-room Bungalo) ni 2 Opopo Ozuba Asaba (Onuja), ni ina jo kanle rau-rau.

Iya Onile re, Iyafin Eunice Agu, ti oko re ti ku, ni o sigbo pe ko si nile, o ti lo si Ibo fun odun Keresimesi.

Nnene Agu, omobinrin ono odun merinla ti o nlo si ilewe giga ni o nkilo pelu omi loju wipe gbogbo nkan ini ebi awon ni o ti raun nile iwe. Pupa oro re, o so wipe ako nibi ti ao sun ki a ma se ri nkan ni wa.

Ogbeni Elijah Ubat, akowe oba ti o ngbe ile na ni agbo pe o ti lo fi ranmi Ke ni Kalaba, gbogbo eru re Pojona. Awon olopa nwadi ina na lowo.

## Aj'iya le Ori Iya.

SPAIN– Oko efurafu kan ti o jalu awon ero ti o pejo lati gba awon Moto ak'eru ti o ko nkan iran. Iowo wa fun awon ti jamba emi ti o kun akunya se ninu osu ti o koja, ni nwon so wipe o to ogun enia ti oko efurafu na pa, awon ti o si farapa pupo yio le ni ogota enia.

Nje, ajiya le ori iya na ko ni eyi ? Awon Yoruba ma npa lowe wipe "Iya di meji, afi eda pa iru epon ada se, iru lo, epon lo."

Ki Oluwa sowa lowo orisirisi jamba aiye.

# OHUN IYANU ODUN TITUN

EKO– Ekun'wo Iwe Ase fun Moto, ak'eru ati awon moto ayokele ti faji, awon moto nla ati kekele ti o jade ninu iwe ikede ijoba ninu ose yi dabi igbati Ijoba wa fi ohun iyanu se odun titun fun ilu.

Afikun owo Iwe Ase Moto na bere lori sile marun lori poun kan fun keke Alupupu ologere d'ori sile medogun lori Poun kan fun moto ayokele ti faaji fun iye ti awon ti nsan tele ri.

Rakanna ni afikun owo ti moto ak'ero ati ak'eru nla goke bi sile merin-din lori Poun kan iye ti nsan tele ri.

Awon afikun owo watunse Iwe Ase oko wiwa fun awon awamoto ati Iwe Ase ti o ba sonu lati gba omiran ati wiwon Moto lati mo bi o ti wiwo si, ni gbogbo ire ti le owo si.

Ami afikun awon agbowo inu moto ni nwon fikun owo re di sile mewa. Afikun owo na yio bere ni ojo kini osu January odun 1962.

---

## ITAN OLE
Lati owo F. O. Noble

Ole ya, oloja gbo Ole Afajo.
O ni ojo iba je ro k'on raye sun.
A ki pe ki ole ma sun.
Ojo ete re 'ku si dede.

Ole gbo t'yan, o so ijoko mora,
O gbo toto o jade nu pepeereperé,
Ole ko sagi logbe, ko ta ogoro lofa,
O de idi ope o gbe u soke, ofe ni re,
Ojo ere ni ere ndun ole,
Iba wole ko jade.
Yio se jade, ayo nko apo itiju nko, nibo ni yio fi ko si?
Ole nfi ibaje se ayo
O nse afewo fa ise.
Beni ise ko gbo ekun, ebi jare ole.
Ibi eni nsise ko raye joun,
Ni ebi npa ole fotoforo
Ole kelu e o ile ko si ohun je
O da ile onil re o dero ewon.
Ibi Ole nsun to nta Ogiri n ya
Ni ogiri ti arati ki ako ti ko
Igbati ojise ntere napon she
O'e n'la eso ninle, o ntoro je kiri
Edumare ma je ti a yan ole enia
Maje ti a bi Ole lomo
Maje k'a bi Ole se ibatan
K'a ma tawo nina ere Ole.

---

E ma Ka Iwe Irohin
Eleti-Ofe
ELETI-OFE D'ARABA

## Olu Omojaguda W'ewon

Ebute-Meta-- Idowu Olu, ti o nṣe iṣẹ ọmọ jaguda ti adape orukọ rẹ ni ede oyinbo nj: "Iron Rod" ti a le tumọ si Yoruba bayi "Koṣe ṣe" ni adajọ Kotu Ebute Ju sẹwon osu meji-din-logun ni ọsẹ tokọja fun ẹsun ole.

Awon ọlọpa sọ wipe Olu wọ Sobu Iyafin Vera Crus lọ pe on fẹ ra siga lọwọ ọmọb'nrin kekere kan leri ipatẹ, o si ji panu kan ti owo ponun meji wa ninu rẹ gbe, jagun f'ẹsẹ fẹe.

Nigbati nwon kegbe ole, ole, awon aladugbo ati ero ti o nkejal'o ba won le Olu mu. Adajọ sọ wipe awon enia ko ni ni ifọkanbale bi iru Olu yi ko ba si ni ipamọ, nitorina ki o lọ ẹwon oṣu meji-din-logun

## Ipade Igbimo Keji-din-logbon Ijo Babalawo

(O bere ninu iwe wa ose to koja)

Ipade pari ni agogo mejila ku iṣeju medogbon gbogbo Awo si fi ori le afin iti lọ foju kan Alaiyeluwa Oba Okuku. Nkan bi ọgbon iṣeju ni Alaiyeluwa fi ba wa sọro iṣiri nipa itọju ati akojẹ ọrọ na Ifa ati bi o ti je ohun ajogun ba wa atipe o je oro aiyeraiye" ti o kun fun ogbon ti enioye lori ati imo otito ti o ye koro ati be be lo.

Awon oro Oba yi je iyalenu fun gbogbo "Ajo to-be-ge ti gbogbo Awo si fi ohun kan ṣabere pe nje iru Oba Alaiyeluwa yi si wa ni orile ede "Ku-Otu-Jire?

Wo yoku loju ewe karun

## OLOTU IJOBA WA TAJO DE

EKO - Olotu ijoba Apapọṣe, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa pada de lati ilu Guinea ti o ti lọ pẹlu awon ẹmẹwa rẹ, lati ibewo Olotu ijoba ilẹ Guinea Alakoso Sekou Toure ni ojo ose to koja.



Olotu ijoba ile Nigeria sọ wipe on kun fun ireti wipe awon Alakoso ti o se ipade ni Kasabulanka yio wa si ipade ti ilu Eko ninu oṣu ti o mbo.

O tun tesiwaju, wipe abewo ti on lo ṣe nilu Guinea kọja leko, o wun lori o si wuld pupo' o fi kun pe awon enia ile Guinea feran enia nwon si ninu rere.


E ma se F'omi Sere




## OKU'JA WOLU

NIGBATI AJỌ KO BA A, TI AWỌN TI ORA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO SE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONṢOWO LE SE TI ỌJA RE YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe.**

## Omo Odun Meji Jabo Lehin Iya Re Sodo.

ONITSHA - Omokunrin omo odun meji ni o jabo lehin iya re sodo Niger ti o si ri sinu omi ni ojo Alarub (Wednesday) ose yi.

Iya omo na ti n o nje Rametu, woko lati Onitsha nlo si Asaba nigbati oko de agbami ni omo yobo kuro lehin re sinu omi.

Rametu paapa, awon gbe pada lo sile ninu ilu Onitsha fun itoju ara ti o fipa papo nigbati o ndu lati ye omo re ninu odo.

Irohin miran tun so wipe Omokunrin, omo odun mewa kan, Raphael, ti ode kan fi pe malu igbo, nigbati o ti nja ewe ninu igbo, o si ta nibon. Nwon ti gbe lo sile Alaisan, sugbon ose kan aiye ese kan oran ni o wa.

## Kotu Ko Ejo Ti Balogun Pe Olowoyin

ILORIN - Ninu Kotu Giga ti ile Ariwa, ti nwon se nilu Ilorin, ni ojo Alaruba (Wednesday) ose yi ni Adajo Skinner ti ko ejo egbedogbon ponun (£5,000) ti Alhaji K. Sanni Balogun, Alaga egbe Olomi (N.P.C.) Nilu Offa pe Ogbeni F.I. Olawoyin ti ise akowe egbe Afenifere (A.G.) nile Ariwa, Nigeria, wipe o ba on loruko je, ni iti o ti nse ikede ni gbangba ti o pe on ni Ole ati Onitanje enia ni ojo kedogun osu November, ti odun tokoja.

Ngbati nwon pe ejo na ni Kotu, Ogbeni T. A. Hastrup ti o nso ejo fun Loya Olowokofoyeku ti o wa fun Balogun, so fun Adajo wipe ki o ye ejo na sigba miran nitoripe asiwaju on ti yi se ejo na ni idiwo ti ko fi le wa.

Oloye A.M.A. Akinloye Loya Ogbeni Olawoyin tako oro re, o ni ki Kotu fawe ejo na ya. Ogbeni Adajo Skinner ti o joko lori ete idajo so wipe Kotu ko tun le ye ejo na mo, nitorina, on fagile ejo na pelu ponun meje ati sile meje, owo inawo ete nisisan fun Ogbeni J. S Olawoyin Olawoyin.

Nwon ti raba ojo yi ko to osu meta nisisiyi.

## OKUNRIN TO SA IYAWO RE LADA W'EWON

IJEBU - ODE Adajo Kotu Kekere nilu Ijebu-Ode ni o sa konbon ewon ose meji-din-logun mo Omotayo Ogunfuwa lori fun ti o wipe o sa iyawo re lada ni ereke, kepa ati ni lebeje.

Awon olopa so wipe Ogunfuwa ti o ngbe ile ana re ni Odogbolu nitosi Ijebu-Ode ni ija dapo pelu Oshenaike iyawo re nitoripe o sakiyesi wipe iyawo na nda on, o si sa l'ogbe.

Ogunfuwa so ni Kotu wipe on lo si Eko sugbon nigbati on pada de ni ojo na ni on ba okunrin kan pelu iyawo on ninu iyara won. Eyi ni ohun ti o fa sababi ti on fi sa iyawo on na lada.

## Ola Ng'ori Ola Oye Ng'ori Oye

EKO-- Olola nla Dokita Nnamdi Azikiwe, Gomina Gbogbo-gbo ati Alase Pataki ile Nigeria pada si Eko ni ojo ose tokoja lehin ifijoye re gegebi Alakoso Ile Eko Giga ti Nigeria ni Nsukka, (Chancellor of the University of Nigeria, Nsukka) ni ojo Satide.



Ninu oro Olola nla Dokita Azikiwe nidi oko ofurufu ni Ikeja, o so fun awon Oniwe irohin wipe on gba ifijoye on si isele nla pataki ninu igbesi aiye on. Awon Oloye Onifila Funfun ati awon enia pataki ni o lo pade re nibudo oko ofurufu ni Ikeja.

## ELETI - OFE D'ARABA

## Ipade Igbimo Keji-din-logbon Ijo Babalawo

(O bere ninu iwe wa ose to koja)

Lehin eyi ni awise Ak we gbegbe-ile Oloye Ogi ri Gbadebo D sumo fesi si awon oro ti Oba so. Alaga Gbogbo-gbo O l o y e Ogbeni Ow omi A fun s dupe o si wure fun Oba, awon l'oye ati awon emewa Oba ati gbegbe ilu ata'n.

Ki a to pari oro ni siso li eru agbon iyan, agbon eko, agbon eba, ikoko obe eran igbe ikoko obe malu, agbe emu, agbe ogoro, agbe otika oti al po onigun merin ati agbon obi funfun konagbo-ko gba o ti fi Oba meri le-egbati owo lel A bali kato pelu. Awon lioye ilu na wa fi ok -merinle logbaji pelu. Awon awo Okuku pare w tun bere si k pali oti Beer ati igo oti funfun onigun merin si l e. Onje ajeti, emu amuti, bakanna ni oti amuti.

Olokuku E ku alejo, E u ikofi, If ake nyin o

Kabiy s A k' enyin om al ta u at I E ku ori ti awon edo o b a m'jeli awa y, L t o Ob unmo at mo v ni a o e e meleli nwo y t aseti, ugbon "Iwi" tun wa g e nwon tiyo.

(Iyoku di ose to mbo)

## Opoulo Omo Sonu Nile Alabiyamo

Opoula' omo titun kan ti nwon sese bi sin ile Alabiyamo ti nwon pe ni At nomo M ern M ternity Home," Mushin, ni ale ojo ose ti o koja ni di awati ich n akati mej ti iya omo re bi.

Nigbati Ol t ju alaisan t o wa ni ile Alabiyamo na lo so fun awon olopa ni awon bere ise lo lesekese Lehinti awon olopa ti se wahala bi wakati mejila ni irohin kan wor, ni n w n wa lo t u le kan ti o wa n won ib so mej si ile Alabiyamo n ri nwon le ri omo titun ti nwon ji gbe lo na ati enini o jgbe.

(Wo yoku loju ewe kefa)

## EBUN GOLU FUN OMOBINRIN TI O NKOSE



Pauline Arnold, omobinrin t i a n w o ninu aworan y i ti o r s e nile ise Letriki ni Dorset, England, ni emiti o n i ojo pataki kan ninu osu December yi ti yio lo fi gba ebun Golu ni Afin James lowo Olola ulo Duke ti Edinburgh ti n nla London.

Pauline n i omobinrin kansoso t i o nko ise ero ile ise Letiriki e n s i n i omobinrin ti yio koko gba Ebun Golu na.

## Ipade Isowopo Awon Ijo Elesin Isese Enia Dudu Nilu Imota

Isowopo awon Ajo Elesin isese enia dudu (The Ancient Religious Societies of African Descendants Association) se ip de pataki ni ilu Imota ni ojo Aiku ti nse ojo kankandilogun odun yi (Sund y 19th of November 1961) Oba Al y luw e ejo Ranada Im ta n i o se Alaga p de Ipade a si bere n agogo (10 ) o w s g a n Ol ye E bo Ai r E O ye O d p k Ol e D s mu Ol t l L k reda l ye P k y S j im t u Ikeredu, Fasanya Arije, ati awon opolopo enia pataki-pataki.

(Wo yoku loju ewe kefa)

OPO TYRE MOTOR

TERCO

- TAYA MOTO TI A SO DI TITUN
- TI OWO RE ROJU
- TI OJA RE TA
- TI O SI NI AGBARA PUPO

Wa Fun Tire Ni Sobu Wonyi :-

NIGER MOTORS

ODUNLAMI STREET, LAGOS.

JOE ALLEN

TINUBU STREET, LAGOS

Faramobi Stores

NO. 60, KOSOKO STEET, 98 TOKUNBO ST, ati NO. 31, GREAT BRIDGE ST.

PHONE - 23727 LAGOS NIGERIA

Ou ni awon Onibara ti o gbon ora.

CHRISTMAS

CARPET

SALE

Special Offer Closing on the 30/12/61.

Buy NOW at the Most favourable Prices

| SIZE | FIXED PRICES | SALE PRICE |
|---|---|---|
| 9' x 12' | £35 | £25. 15 |
| 9' x 101/2' | £31. 10 | £22. 10 |
| 9' x 9' | £28 | £19. 5 |
| 71/2 x 9 | £22 | £16. 10 |

REAL HOT BARGAIN

NOT TO BE REPEATED

LEVENTIS

DEPARTMENT STORE

MARINA

## Ipade Isowopo Awon Ijo Elesin Isese Enia Dudu Nilu Imota

(O bere loju ewe karun)

Ninu Ipade yi ni Akowe Isowopo na ti ka Iwe ase titun ti Isowopo yi gese gba li odo ijoba Apapo Nigeria (Certificate of Incorporation under Land (perpetual Succession) Ordinance) ni oruko awon Apapo Ijo Elesin Isese Enia duda (United Religious Organisation of African Descendants) eyiti nse Igbimo ti isowopo yi da sile lati le ma se eto lati le ma da awon Ile Eko (Schools and Colleges) ati Ile Ijoba (Churches) sile yipo gbogbo ile Nigeria. Isowopo yi si tun ro lati tun ni awon orisirisi Igbimo ti y'o ma ba okoran ninu awon eto Isowopo yi (Aims and objects of the Association) ko.

Isowopo na si tun ti ni Ile ni Yaba ni ilu Eko, lati fi da Ile eko ati Ile Ijoba sile. Oba Alaiye'uwa Renodu Imota si tun se ileri lati fun Isowopo yi ni Ile lati fi ko Ile Eko Awon Olukoni (Teachers Training College) ati Ile Ijoba (Churches) nigbati asiko na ba to.

Awon Asoju ti awon ti awon ilu orisirisi wa si ipade yi to edegbeta (500). Lehin ipade yi awon Eka Onisese ilu Imota fi ijo ati ayo ati ilu ti awon wa se ipade na lorun. Awon Oloye ti a da oruko won si isale yi se inawo ni opolopo, Awon ni Oloye D Shofarin Aare Magodo, Oloye Okelarin, Onimole Logunmogbo, Oloye Aise Odunran Magodo, Oloye Abasan Onimole, Oloye Ogunfolabi, Oloye Ola Abiyomi, Ogbeni Ben Adejo, Ogbeni Ajala ati Oloye Araba Imota.

Oba Alaiyeluwa Renodu Imota na si tun se awon asoju na alejo. Ajo Elesin Isese Enia dudu (Ijo mimo) ni o se isileti lati tun Odu Mimo. Lehin eyi awon Babalawo ti won ti Ikorodu wa, ati awon Babalawo ti ilu Imota ati ti ilu Gbogbo fi agogo Ifa (ora lehin ipade na gbogbo ilu si odun yungba.

Isowopo na si fi ipade ti o mbo si ilu Iperu ni osu keji odun 1962, February 11, 1962) ni ojo kokanla osu. Won si tun kede ki eye gbogbo awon Ajo tabi Ijo Elesin Isese ye si ilu Iperu na.

Abere, Aboye.

## Oponlo omo Sonu Nile Alabiyamo

(O bere loju ewe karun)

Iya ti o bi omo na nje Idayatu Lamina ni Opopo ona Isale, nigbati awon gbe omo re wa fun nibiti oko re Ogbeni Lamina gbe ntu ninu, o so wipe on kole so bi ayo okan on tito, awon olopa ni on dupe fun gidigidi.

Ni ojo Alaruba ni awon mu abileko obinrin kan, Sherifat Olukoya wa siwaju adajo Kotu kekere Ikeja, fun esun wipe o ji omo gbe ninu ile Alabiyamo ni Mushin ni ale ojo ose tokoja.

Adajo fi gbogbo ejo re si ojo Alaruba oso ti o mbo, sugbon bi awon olopa ti nfe mu jade ninu apoti-eri, ni Sherifat kigbe wipe on ni oro lati ba adajo so. Nwon si dapada sinu apoti-eri. O so fun adajo pe niwon ose die sehin ni oyun baje lara on sugbon nigbati on so fun oko on wipe oyun na baje oko on na so pe on ni lati wa omo walonakona. Nitori ki nle te ife re lorun ni mo se ji omo na gbe. Adajo so fun wipe gbogbo aroye re ni on yio gbo nigbati ejo re ba bere.

Printed & Published By The Union Printing & Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No 23370